# Àyẹ̀wò Àbùdá àwọn Arẹ́nijẹ nínú àwọn Ìwé Eré-Onítàn Adálórí Ìjàjàgbara

**Ọlátúndé Adélẹ́yẹ Adéyẹmọ,** ***Ph.D.***
*Department of Nigerian Languages and Literatures*
*Ọlábísí Ọnàbánjọ University, Àgọ́-Ìwòyè*
*aoadeyemo2005@yahoo.com*

> …àwọn ológún ilé, ọlọ́gbọ̀n ọkọ̀, ẹlẹ́gbẹ̀rún aṣọ ìbora…àwọn tí wọ́n jẹ tó, tí wọ́n jẹ ṣẹ́kù tí ọ̀rá fẹ́rẹ̀ lè máa kán só-só-só lára wọn…àwọn aṣánilọ́gbẹ́ abẹ́nú, àwọn alọ́nilọ́wọ́gbà, àwọn afúnnigbẹ, àwọn ajẹnirun…
>
> (Òkédìjí, 1973: 29)

## Àṣamọ̀

*Lọ́pọ̀ ìgbà ni àwọn olùdìbò máa ń kìka àbámọ̀ bọ ẹnu lẹ́yìn tí wọ́n bá yan àwọn olóṣèlú sípò tán. Ìdí ni pé tí ọ̀pọ̀ àwọn olóṣèlú náà bá dé ipò tán, wọ́n á wá jẹ gàba lé àwọn ènìyàn lórí, wọ́n á sọ wọ́n di ẹ̀gúsí tí ó mú ọbẹ̀ dùn tán tí èèpo rẹ̀ wáá di ohun àìjíírí. Nítorí náà ni iṣẹ́ yìí ṣe dá lórí àgbéyẹ̀wò àbùdá àwọn arẹ́nijẹ́ nínú ìwé eré-onítàn a-dá-lórí ìjàjàgbara mẹ̀kúnnù lọ́wọ́ arẹ́nijẹ. Àwọn ìwé tí a yẹ̀wò ni Rẹ́rẹ́ Rún, Ayé Yẹ Wọ́n Tán, àti Orí Mẹ̀kúnnù. Ohun tí a wòye gẹ́gẹ́ bí àbùdá àwọn arẹ́nijẹ ni oríṣìíríṣìí ìwà tó wà lọ́wọ́ àwọn arẹ́nijẹ tí wọ́n fi ń da àwọn mẹ̀kúnnù láàmú. Ojú tíọ̀rì Marx tó jẹ mọ́ ìjẹgàba àwọn arẹ́nijẹ́ ni a fi wo iṣẹ́ náà. Àwọn àbùdá yìí ló ń tọ́ka sí pàtàkì ṣíṣe àyẹ̀wò fínnífínní nípa ìhùwàsí ẹni a ó bá yàn sípò adarí tàbí ti òṣèlú, pàápàá lásìkò tí àwọn olóṣèlú bá ń polongo ìbò.*

**Kókó Ọ̀rọ̀:** Arẹ́nijẹ, Eré-Onítàn, Ìjàjàgbara, Tíọ̀rì Marx

## Ìfáárà

Ìwà à ń rẹ́nijẹ kì í ṣe tuntun ní àwùjọ wa, ó pẹ́ tí ó ti wà bẹ́ẹ̀. Nínú àwùjọ ni a ti rí arẹ́nijẹ àti mẹ̀kúnnù bákan náà. Èyí ló mú Henderrison (1976: 374) sọ pé:

> There were always bound to be two classes in society, a ruling class which controlled the means of production and a poor, oppressed class of wage earners.
>
> Ọ̀ràn-an-yàn ló jẹ́ láti ni àwọn ọ̀wọ́ méjì ní àwùjọ, àwọn ọ̀wọ́ tó ń darí tó tún n ṣàkóoso ohun àmúṣẹ̀dá àti àwọn ọ̀wọ́ tí à ń pọ́n lójú tí wọ́n jẹ́ òṣìṣẹ́.

Ẹ̀wẹ̀, a lè rí 'àbùdá' gẹ́gẹ́ bí ìṣesí, ìhùwàsí tàbí àwọn nǹkan tó ń fi ènìyàn tàbí ohun kan hàn tàbí tí ó yà á sọ́tọ̀ kúrò lára àwọn nǹkan mìíràn. Èyí lè fara hàn nínú ìṣe tàbí ìhùwàsí irú ẹni tàbí ohun bẹ́ẹ̀. Ní ti ẹ̀dá ènìyàn, irú àbùdá yìí ló máa ń sọ irú ẹni tí onítọ̀ún jẹ́ àti àwọn ìhà tí ó lè kọ sí àwọn ìṣẹ̀lẹ̀ kan. Ẹ̀dá ènìyàn lè ní àbùdá rere tó bẹ́ẹ̀ tí onítọ̀ún fi máa jẹ́ ìtẹ́wọ́gbà láàrin àwùjọ, bẹ́ẹ̀ ni àbùdá mìíràn wà tí kì í jẹ́ ìtẹ́wọ́gbà ní àwùjọ. Irú àbùdá yìí tún lè jẹ́ bí i dídé fìlà kò-kàn-mí tàbí dídágunlá sí ọ̀rọ̀ àwọn tí ìyà ń jẹ, jíjókòó lé ẹ̀tọ́ àwọn ènìyàn, àìní omi àánú lójú, àìlè dúró lórí ìlérí, àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ. Irú àbùdá yìí ni a ó gbé yẹ̀wò nínú iṣẹ́ yìí.

Bí a bá wo àwùjọ, bóyá ni a lè rí ẹ̀ka kan ní àwùjọ yòówù tí a kì í ti í rí ìwà ìrẹ́nijẹ. Adéyẹmọ (2005) ṣiṣẹ́ lórí ìjìjàgbara nínú eré-onítàn Yorùbá tó sì gbé èrèdí ìjìjàgbara àti àwọn tí à ń rẹ́ jẹ wo. Ó ṣe àkíyèsí nínú iṣẹ́ náà pé ọwọ́ tí àwọn tó wà nípò àṣẹ ń gbé ló fa ìjìjàgbara àwọn ọ̀wọ́ tó kù díẹ̀ káàtó fún. Bákan ẹ̀wẹ̀, Adélékè (2005) náà ṣiṣẹ́ lórí ohun tó máa ń fa ìfagagbága

láàrin olówó àti mẹ̀kúnnù bí i wíwá ọ̀nà àti tẹ mẹ̀kúnnù lórí ba, fífi ọwọ́ ọlá gbá ni lójú àti ìjẹgàba èyí tó máa ń fa ìjìjàgbara. Gbogbo àkíyèsí yìí náà ló wà nínú ìṣesí àwọn arẹ́nijẹ.

Yàtọ̀ sí èyí, iṣẹ́ Oyèbámíji (2015) náà dá lórí àwọn adarí, ìjẹgàba àti òmìnira àwọn mẹ̀kúnnù. Ó ṣàkíyèsí pé jíjá ẹ̀tọ́ ẹlòmíràn gbà láti bọ́ sí ipò gíga, síṣi agbára àti ipò àṣẹ lò, àti fífòòró àwọn ènìyàn wà lára ọ̀nà tí àwọn adarí máa ń lò lórí aráàlú. Bí a bá wo gbogbo àlàkalẹ̀ yìí, ń ṣe ló ṣe rẹ́gí pẹ̀lú àbùdá àwọn arẹ́nijẹ. Bọ́lárìnwá (2016) náà sọ̀rọ̀ lórí ìkọlura tó máa ń wáyé láàrin àwọn olóṣèlú pàápàá ní orílẹ̀-èdè Nàìjíríà. Ó ṣàfihàn ohun tó máa ń fa ìkọlù bíi níní ìfẹ́ sí ipò gíga, fífẹ́ẹ́ máa fọwọ́ rọ́ àwọn ènìyàn kan sẹ́yìn bí ẹni tí kò ṣe pàtàkì, ìjẹgàba àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ. Bákan náà ló ṣàkíyèsí lílo tọ́ọ̀gì, ìbanilórúkọjẹ́, ṣíṣe tinú ẹni láìbìkítà bóyá ó dára tàbí kò dára gẹ́gẹ́ bí ìṣesí àwọn adarí. Bí a bá wò ó dáradára a ó rí àwọn ohun tí a kà sílẹ̀ yìí gẹ́gẹ́ bí èyí tó jọ ìṣesí àwọn arẹ́nijẹ. Bí àwọn adarí ṣe ń rẹ́ ara wọn jẹ náà ni wọ́n tún ń rẹ́ àwọn mẹ̀kúnnù jẹ.

Tóbi (2015) sọ̀rọ̀ lórí bí àwọn aṣíwájú tàbí adarí ṣe ń dá kún ìṣòro aráàlú pàápàá ní orílẹ̀-èdè Nàìjíríà àti ìbáṣepọ̀ tó yẹ kó wà láàrin aṣíwájú àti ọmọ ẹ̀yìn. Ó rí ipò aṣíwájú bí èyí tí a ti ń retí ìwà òtítọ́, ìfarajìn, àfojúsùn, àkóyawọ́ àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ. Àkíyèsí yìí dára, ṣùgbọ́n ìbéèrè ni pé ṣé gbogbo àwọn adarí ló ní àbùdá yìí? Bó bá rí bẹ́ẹ̀, à ń rẹ́nijẹ ìbá ti máa wáyé. Okùnadé (2008) náà ṣàkíyèsí èyí, ṣùgbọ́n ó rí i pé ayé fàmílétè n tutọ́ ni àwọn asíwájú mìíràn máa ń jẹ èyí tó máa ń fa ìjákulẹ̀ wọn. Bí a bá sì wò ó, tí arẹ́nijẹ bá ti lé ewúrẹ́ mẹ̀kúnnù kan ògiri, ń ṣe ni yóò yíjú padà. Èyí ló máa ń fa ìjìjàgbara kúrò lọ́wọ́ ìṣèjọba arẹ́nijẹ.

Ní àfikún, Achebe (1983) rí ìjákulẹ̀ aṣíwájú bí àìlè kún ojú òsùwọ̀n ẹni tó fẹ́ bọ́ sí ipò. Ó ṣàkíyèsí pé òbítíbitì owó tó wà fún ìdàgbàsókè ìlú ni àwọn tó wà nípò àṣẹ máa ń kó sápò araa wọn. Ìnira ni ìwà yìí máa ń mú bá ará ìlú. A lè rí arẹ́nijẹ níbí yìí bíi aninilára. Bákan náà, gbogbo àwọn ìwà-ìbàjẹ́ àwọn adarí yálà ológun tàbí ìjọba adìbòyàn ni Ogbeidi (2012) àti Adétóyè (2014) rí nínú iṣẹ́ wọn. Àkíyèsí wọn ni pé ń ṣe ni olúkúlùkù ń ro oko sí ọ̀dọ̀ ara rẹ̀ pẹ̀lú ìfagagbága bí ọ̀rọ̀ oníkálùkù yóò ti ṣe máa pọ̀ sí i. Bí a bá sì wò ó lóòótọ́, ara ìhùwàsí àwọn arẹ́nijẹ ni èyí nítorí owó kì í tó olówó ni ọ̀rọ̀ àwọn arẹ́nijẹ, wọn ò mọ 'kò tọ́'. Kò sí ọ̀kan nínú àwọn iṣẹ́ tó wà nílẹ̀ yìí tó dá lórí àbùdá àwọn arẹ́nijẹ ní kíkún, àlàfo yìí ni iṣẹ́ yìí fẹ́ dí.

## Ìtàn inú ìwé kọ̀ọ̀kan ní ṣókí

Ní abala yìí, a ṣe ìsọníṣókí ìtàn inú eré onítàn tí a ṣà yàn fún iṣẹ́ yìí.

### *Rẹ́rẹ́ Rún*

Alàgbà Ọládẹ̀jọ Òkédìjí ni ó kọ Rẹ́rẹ́ run. Ní ìbẹ̀rẹ̀ eré-onítàn yìí, àwọn òṣìṣẹ́ bẹ̀rẹ̀ sí í kọ orin òwe tó dá lórí ìṣòro tí wọ́n ń là kọjá. Ohun tí Láwúwo tó jẹ́ olórí òṣìṣẹ́ ń béèrè fún àwọn ọmọ ẹgbẹ́ ni ìgbé ayé tó dẹrùn. Lára rẹ̀ ni ẹ̀kúnwó, níní aṣojú nínú ìgbìmọ̀ àti dídín owó orí tí àwọn ènìyàn ń san kù.

Ní ti Onímògún àti àwọn ìjòyè rẹ̀, àlá tí kò lè ṣẹ ni ìbéèrè àwọn òṣìṣẹ́. Ojú aláìmoore ni wọ́n fi wo òṣìṣẹ́, wọ́n sì gbà pe ìfẹ́ láti wà ní ipò kan náà pẹ̀lú àwọn aláṣẹ ni ó múmú láyà wọn. Níwọ̀n ìgbà tí ìbéèrè àwọn òṣìṣẹ́ kò ti di mímúṣẹ tí wọ́n sì ń gbé ìgbé ayé tí kò bójúmu, ohun tí wọ́n gùn lé ni ìyanṣẹ́lódì. Dípò tí àwọn aláṣẹ ìbá fi dáhùn sí ìbéèrè àwọn òṣìṣẹ́, ṣe ni wọ́n fi

Láwúwo tó jẹ́ adarí àwọn òṣìṣẹ́ sí àhámọ́ èyí tó tún pa kún ìyanṣẹ́lódì náà. Lójú ẹsẹ̀ ni àwọn òṣìṣẹ́ ń bèèrè ìyọ̀nda adarí wọn pẹ̀lú ìlérí pé wọn kò ṣetán láti gba ìdarí lọ́dọ̀ ẹlòmíràn àyàfi Láwúwo. Kì í ṣe bẹ́ẹ̀ nìkan, àwọn òṣìṣẹ́ tún ṣètò ẹ̀dáwó láti gba agbẹjọ́rò tí yóò ṣojú wọn ní ilé ẹjọ́. Nínú èyí náà, a rí akitiyan ìyá-ẹgbẹ́ òṣìṣẹ́ tíí ṣe Wúràọlá lórí ohun tó ń lọ láàrin àwọn òṣìṣẹ́.

Láti da akitiyan ẹgbẹ́ òṣìṣẹ́ rú, Onímògún pé Láwúwo lọ́nà àti tù ú lójú. Níwọ̀n ìgbà tí ohun tí àwọn aláṣẹ fẹ́ fi tu Láwúwo lójú kò kan àwọn òṣìṣẹ́ yòókù, Lawúwo takú délẹ̀ láti tẹ̀síwájú pẹ̀lú ìgbésẹ̀ mìíràn tó le ju ti àtẹ̀yìnwá lọ. Nígbà tí ẹ̀kọ kò ṣojú mímu mọ́ fún àwọn aláṣẹ lórí ọ̀rọ̀ àwọn òṣìṣẹ́, wọ́n dọ́gbọ́n fa ojú Ìdòwú tó jẹ́ ọ̀kan lára àwọn òṣìṣẹ́ mọ́ra tó sì di agbẹ̀yìnbẹbọjẹ́ fún àwọn òṣìṣẹ́.

Nípa akitiyan Ìdòwú ni a fi lu Morẹ́nikẹ́ ní jìbìtì owó tó jẹ́ ti Láwúwo. Nígbà tí kò mọ ohun tó máa ṣe mọ́ àti ohun tó fẹ́ sọ fún Láwúwo, ó lo òògùn tó kọjá sísọ tó sì tipa bẹ́ẹ̀ tẹ́rí gbaṣọ. Ìṣẹ̀lẹ̀ yìí ló fà á tí orí Láwúwo fi yí tí òun náà sì ń sọ kántan-kàntan, irú ipò yìí kò sì fi ààyè sílẹ̀ fún un láti tún máa darí àwọn òṣìṣẹ́ mọ́. Gẹ́lẹ́ tí ọ̀rọ̀ rí báyìí ni àwọn aláṣẹ yan Ìdòwú gẹ́gẹ́ bí adarí àwọn òṣìṣẹ́ tuntun. Púpọ̀ lára àwọn òṣìṣẹ́ ni wọ́n dá dúró nígbà tí àwọn tó kù ń pariwo lábẹ́ ìsìnrú tó le koko bí ojú ẹja.

Ní ìparí, ó ṣe ni láàánú pé bó tilẹ̀ jẹ́ pé àwọn òṣìṣẹ́ sa ipá lórí ìbéèrè wọn, ìjákulẹ̀ ni wọ́n bá pàdé. Àwọn aláṣẹ fi kún wákàtí tí wọn fi ń siṣẹ́, wọ́n dín owó osù wọn kù, nǹkan sì burú fún wọn ju ti ìṣaájú lọ.

## *Orí Mẹ̀kúnnù*

Alàgbà Fánilọ̀lá ni ó kọ eré onítàn *Orí Mẹ̀kúnnù.* Lẹ́yìn tí Ọba Ìlú Tìkàlójù ti wàjà, àwọn afọbajẹ pinnu láti yan ọba tuntun. Ohun tí wọ́n ṣe ni láti sọ fún gbogbo ìdílé tó yẹ fún ipò ọba kí wọn fi orúkọ ránṣẹ́. Ní ìdáhùn sí ìpè yìí, orúkọ Oyekan àti Adékànmíbí ni àwọn ìdílé tí oyè kàn fi ránṣẹ́ sí àwọn afọbajẹ. Gẹ́gẹ́ bí ìṣe àtẹ̀yìnwá, ó di dandan láti bèèrè lọ́wọ́ ifá láti yan èyí tó tọ́ nínú orúkọ méjéèjì. Lọ́gán náà ni àwọn afọbajẹ pe Babaláwo tí wọ́n sì fi àwọn orúkọ méjèèjì síwájú rẹ̀. Ní ìkẹyìn, orúkọ Oyekan ni ifá mú.

Bí Adékànmíbí tó jẹ́ ọ̀kan lára àwọn tó ń du ipò ọba ti rí i pé ipò ọba kò ní tó òun lọ́wọ́, ó lọ sọ́dọ̀ àwọn afọbajẹ kan pẹ̀lú owó ẹ̀yìn. Àwọn afọbajẹ yìí gba ẹ̀bùn náà pẹ̀lú àdéhùn pé bí ipò ọba bá bọ́ sí Adékànmíbí lọ́wọ́, kò ní tan iná wo iṣẹ́ láabi tí wọ́n ti ṣe sẹ́yìn nípa owó iṣẹ́ ìlú tí wọ́n ti kó jẹ. Ní ti Oyekan, ó ti pinnu pé ara ohun tí yóò kọ́kọ́ dojúkọ ni ìwà-ìbàjẹ́ àti pé ó di dandan kí àwọn tó bá kó owó ìlú jẹ san án padà.

Pẹ̀lú ìfọwọ́sowọ́pọ̀ àwọn afọbajẹ kan, wọ́n fi Adékànmíbí tí Ifá kò mú jẹ ọba tako ìpinnu ifá. Irú ìgbésẹ̀ yìí kò tẹ́ púpọ̀ àwọn aráàlú lọ́rùn. Ní kété tí a fi Adékànmíbí jẹ ọba tán tó ń bá àwọn ìlú sọ̀rọ̀, ó ní òun ti fi owó kún owó-orí tí wọ́n ń san tẹ́lẹ̀ àtí pé àwọn obìnrin náà sì gbọdọ̀ máa san án. Kò pin síbẹ̀, òun yóò tún ètò ìkówojọ mìíràn ṣe lórí iṣẹ́ tí wọ́n ti gbé síta fún agbaṣẹ́ṣe. Lójú ẹsẹ̀ ni àwọn aráàlù tí takòó tí wọ́n sì ń fẹ̀ kí á tanná wádìí àwọn ìgbìmọ̀ tó kọ́kọ́ wà nílẹ̀ fún ìkówójọ. Ọba Adékànmíbí yọ Ìyálóde bi ẹni yọ jìgá nítorí ó rí i bí ẹni tí kò fọwọ́sowọ́pọ̀ pẹ̀lú òun.

Bí Ọba Adékànmíbí ti rí i pé òun kò jẹ́ ìtẹ́wọ́gbà lọ́wọ́ àwọn ènìyàn, kíá ló ń gbé ìgbésẹ̀ tí yóò fi yanjú àwọn alátakò rẹ̀, ṣùgbọ́n àṣírí yìí tú síta. Ọ̀kan lára àwọn olóyè tó gbà láti ṣe iṣẹ́ yìí ya wèrè tó sì bẹ̀rẹ̀ sí tú àṣírí ìgbésẹ̀ gbogbo tí ọba ti gbé ní ìkọ̀kọ̀ síta. Eléyìí ṣẹlẹ̀ nítorí òkú àwọn tí wọn ti pa ń ṣe ọba ríbo-rìbo. Kíá ni wọ́n ránṣẹ́ sí Babaláwo tó dífá ọjọ́ kìnní tí onítọ̀ún sì sọ fún wọn pé àsìṣe ọba ló ń kó ìyá jẹ é àti pé kò sí àtúnṣe.

Ní ìparí, aáwọ̀ gbogbo di yíyanjú lẹ́yìn tí àwọn ìlú dìde sí kábíyèsí àti ẹmẹ̀wà rẹ̀ nínú èyí tí Ìyálóde ṣíwájú wọn. Ní ìkẹyìn, ọba bá ìṣẹ̀lẹ̀ náà rìn, ọwọ́ tún ba àwọn tó ń ti ọba lẹ́yìn tẹ́lẹ̀. Ayọ̀ ni ohun gbogbo yọrí sí.

***Ayé Yẹ Wọ́n Tán***

Lẹ́yìn ikú Onípo ti ìlú Ìpo, àwọn afọbajẹ gbèrò láti fi ọba tuntun jẹ. Àwọn mẹ́ta ni wọ́n ń du ipò náà – Ṣiyanbọ́lá, Ọládàpọ̀ àti Amúniwáyé. Àwọn afọbajẹ jókòó láti wo èyí tí yóò jẹ́ ìtẹ́wọ́gbà fún ipò ọba nípa yíyẹ ohun tí ọ̀kọ̀ọ̀kan wọn ní lọ́kàn wò láti ṣe fún ará ìlú tí ipò náà bá bọ́ sì wọn lọ́wọ́. Bí ọ̀rọ̀ bá rí báyìí, ohun tí àwọn afọbajẹ máa ń ṣe ni kí wọ́n bi ifá léèrè irú ẹni tó yẹ fún ipò náà. Ní ti eléyìí, ọ̀rọ̀ kò rí bẹ́ẹ̀ rárá nítorí ojúkòkòrò Baṣọ̀run ẹni tí ó ní ẹnìkan lọ́kàn fún ipò ọba náà tó sì rí ìfọwọ́sowọ́pọ̀ àwọn afọbajẹ yòókù. Nítorí náà, orúkọ ènìyàn kan soso ni wọ́n fi siwájú ifá. Èsì tí Babaláwo fọ̀ sí èyí ni pé ifá kò mú ẹni náà rárá, kò sì sí ètùtù tó lè yí i padà.

Ní àtakò sí ohun tí ifá sọ, àwọn afọbajẹ fi Ṣiyanbọ́lá jẹ ọba bí ó tilẹ̀ jẹ́ pé ó kùnà láti mú ìlérí tó ṣe fún àwọn ẹgbẹ́ alájẹṣẹ́kù ṣẹ. Nítorí náà, àwọn ẹgbẹ́ yìí pinnu láti pe ìpàdé. Nínú ìpàdé yìí ni wọ́n ti sọ̀rọ̀ lórí ìgbéṣẹ̀ ọba àti àwọn ìjòyè rẹ̀ tí wọ́n

gba iṣẹ́ lówó gọbọi lẹ́yìn tí àwọn ọmọ ẹgbẹ́ alájẹṣẹ́kù ti gbà láti ṣe é ní owó tí kò gbunpá kí ọba lè rí àyè àti fi owó ṣe àwọn nǹkan mìíràn tó yẹ fún ìlú. Ń ṣe ni ọba àti àwọn ìjòyè rẹ̀ pín àwọn ilẹ̀ náà pẹ̀lú owó tó yẹ fún àtúnṣe ìlú. Ìgbéṣẹ̀ yìí náà kò yọ Adédùn tó jẹ́ olorì ọba sílẹ̀.

Ní bí ọ̀rọ̀ ṣe wá rí báyìí, ṣe ni ọba ń lo àwọn agbófinró láti tú ìpàdé yòówù ká tí àwọn agbófinró sì ń fi páńpẹ́ òfin gbé àwọn ọmọ ẹgbẹ́. Nínú ọ̀kan lára ìpàdé náà ni àwọn tó dira ogun mẹ́ta kan ti já wọlé nígbà tí àwọn agbófinró ń ṣe iṣẹ́ wọn tí wọ́n sì yìnbọn pa Ọládàpọ̀ tó jẹ́ baba ìṣàlẹ̀ ẹgbẹ́ náà. Irú ìgbéṣẹ̀ yìí kò dùn mọ́ àwọn ọmọ ẹgbẹ́ nínú èyí tó fa ìwọ́de àwọn ọmọ ẹgbẹ́ alájùmọ̀ṣe. Lára ẹ̀sùn tí wọ́n fi kan ọba àti àwọn ìjòyè ni ìkówójẹ oríṣìírìṣìí àti ìwà àìdára mìíràn. Bí èyí ti ń lọ ni àwọn tó dira ìbọn fi tipá-tipá mú akọ̀wé ẹgbẹ́ alájùmọ̀ṣe, wọ́n sì gbé e sálọ síbi tí ẹnikẹ́ni kò mọ̀.

Láti fi òpin sí ìwà àìdara tí ọba àti àwọn ìjòyè ń hù, àwọn ẹgbẹ́ alájùmọ̀ṣe ní ó di dandan kí ọba àti àwọn ìjòyè lọ búra níwájú òrìṣà Ìpo. Bí ọba ti mọ̀ pé irú ìbúra yìí léwu púpọ̀, ó tètè ṣètò ní ìdákọ́ńkọ́ pẹ̀lú àwọn tí yóò da ìgbéṣẹ̀ náà rú. Ní ọjọ́ ìbúra yìí, nígbà tí ìbura kan ọba, àwọn kan já wọ ibi ìbúra náà láti dà á rú, àmọ́, wọ́n rí àwọn wọ̀nyí mú. Sámù tí orí kó yọ ló lọ sọ ohun tó ń ṣẹlẹ̀ fún àwọn ará ìlú tí gbogbo wọn sì ya bo ibi ìbúra náà.

Ní ìparí, àwọn ìlú rẹ́yìn ìjọba arẹ́nijẹ lábẹ́ ìdarí Ọba Ṣiyanbọ́lá àti àwọn ìjòyè rẹ̀. Gẹ́gẹ́ bí àkọlé ìwé náà, lóòótọ́ nígbà tí ayé yẹ ọba tán, ń ṣe ló bẹ̀rẹ̀ síí hu ìwà-ìbàjẹ́.

## Tíọ̀rì Lítíréṣọ̀ tó Tẹ̀lé Èrò Marx

Karl Marx àti Friedrich Engels ló gbé tíọ̀rì yìí kalẹ̀. Ohun tí tíọ̀rì yìí ń tẹ̀pẹlẹ mọ́ ni pé ọ̀wọ́ àwọn ẹ̀dá kan ló ní àṣẹ lọ́wọ́ ní àwùjọ tí wọ́n fi ń jẹ gàba lórí ọ̀wọ́ tó kù yálà nípa ọ̀rọ̀ ètò òṣèlú tàbí ti ọrọ̀-ajé (Ọ̀pẹ́fèyítìmí, 1997).

Nítorí náà, àkíyèsí tíọ̀rì yìí ni a lè sọ pé ó gbára lé ìjìjàgbara tàbí ìkọlura agbára. Ohun tó fà aáwọ̀ àti ìlòdì sí ìjọba láti ọwọ́ àwọn tí à ń jẹ gàba lé lórí ni ètò ọrọ̀-ajé aládàáńlá tó fààyè gba ìpínsíṣẹ́ tó sì tún fààyè gba ìmọ̀ ẹ̀rọ èyí tó mú kí ètò okòwò fẹjú síi lọ́nà èyí tí ìtẹ̀síwájú fi ń bá àwùjọ. 'Ṣùgbọ́n' tí ó wà níbi èyí ni pé irúfẹ́ ètò ọrọ̀-ajé yìí fààyè gba ìrẹ́jẹ àti ìkọlura agbára àwọn tó fẹ́ ṣèlú nítorí àwọn tó bá ṣèlú ló lágbára àti mójútó ètò ọrọ̀-ajé (Adéyẹmí, 2006).

Àkíyèsí tún ni pé ọrọ̀-ajé àti ojú àmúwáyé ni ó máa ń bí aáwọ̀ láàrin àwọn aláṣẹ àti mẹ̀kúnnù. Àwọn  mẹ̀kúnnù gbà pé kò sí bí ọ̀bọ ṣe sorí tí ìnàkí kò ṣe àti pé òṣìṣẹ́ kò le wà lóòrùn kí abáninawó wà ní ibòòji. Àwọn aláṣẹ ń sa ipá kí agbára máà bọ́ lọ́wọ́ wọn bẹ́ẹ̀ ni àwọn òṣìṣẹ́ àti mẹ̀kúnnù náà ń làkàkà láti gba agbára lọ́wọ́ ẹlẹ́wù ẹ̀tù pàápàá bí àwọn aláṣẹ kò bá lo agbára náà dáradára nípa pínpín ọrọ̀-ajé bó ti tọ́ àti bó ti ṣe yẹ (Adélékè, 2005).

Lábẹ́ tíọ̀rì yìí, lítíréṣọ̀ gbọ́dọ̀ jẹ́ èyí tí yóò máa gbè lẹ́yìn ìjìjàgbara kí ó sì tako ìrẹ́jẹ àti ìjẹgàba. Ẹ̀wẹ̀, iṣẹ́ lítíréṣọ̀ tún ni láti mú àyípadà tó lọ̀ọ̀rìn bá àwùjọ yòówù. Bámidélé (2000: 16) kín èyí lẹ́yìn nígbà tó sọ pé: "Poem, play or novel should be used as a weapon of change". Èyí túmọ̀ sí pé ewì, eré-oníṣe tàbí ìtàn-àròsọ gbọ́dọ̀ jẹ́ ohun èlò fún àyípadà. Eagleton (1976) náà sọ pé lítíréṣọ̀ máa ń fi òtítọ́ hàn tí ó sì tún lè tako èrò báyéṣerí

àwùjọ kan lọ́nà àti mú ìtẹ̀síwájú bá irú àwùjọ bẹ́ẹ̀. Lára àwọn agbátẹrù tíọ́rì yìí ni Lenin, Mao, Lucas, Goldman, Bredit, Nikolai, Bukharin, àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ.

Louis Althusser náà jẹ́ ọ̀kan lára àwọn abẹnugan tíọ́rì yìí, èrò rẹ sì ṣe pàtàkì pẹ̀lú. Lára àwọn onitíọ́rì ti Althusser gùnlé láti ṣe àfàyọ èrò tirẹ̀ ni Antonio Gramsci àti Jacques Lacan. Nínú àgbékalẹ̀ yìí ló ti ṣàkíyèsí ohun tí àwọn alágbára àti àwọn aláṣẹ máa ń lò láti tẹrí àwọn mẹ̀kúnnù ba kí wọ́n lè baà máa rí wọn lò. Oríṣìí ọ̀nà méjì ló là kalẹ̀ gẹ́gẹ́ bí ọ̀nà tí àwọn arẹ́nijẹ ń gbà ṣe èyí. Àkọ́kọ́ ni èyí tí ó rí bí ìlò ilé-ẹjọ́, ìjọba, àwọn ọlọ́pàá, àwọn agbófinró mìíràn gẹ́gẹ́ bí irinṣẹ́ tí àwọn arẹ́nijẹ ń lò láti tẹrí àwọn mẹ̀kúnnù tó bá fẹ́ tako ìjọba ba. Ohun tí èyí fi rọrùn ni pé àwọn arẹ́nijẹ ló ń darí tí wọ́n sì wà ní òkè téńté. Gbogbo agbára aṣèyíówùú ló wà ní ìkáwọ́ wọn láti lo idà ìṣèjọba wọn lórí àwọn alátakò. Nítorí náà, gbogbo irinṣẹ́ yìí ni arẹ́nijẹ ń lò láti gbo ewúro sí mẹ̀kúnnù lójú tàbí ẹni yòówù tó bá fẹ́ dojú kọ ìjọba wọn. Bó wù wọ́n, wọ́n le gbé irú ẹni bẹ́ẹ̀ tì mọ́lé, wọ́n lè lo ìbọn láti halẹ̀ tàbí tú ìpàdé mìíràn ká tàbí fínná mọ́ alátakò. Èyí ni Althusser pè ní “Repressive State Apparatus” (RSA) (Ohun èlò atẹrí-aráàlú-ba).

Ní ìdàkejì, dípò lílo agbára láti tẹrí àwọn alátakò ba nípa ìlò ọlọ́pàá tàbí agbófinró, àwọn aláṣẹ máa ń lo èrò báyéṣerí láti fi tẹ orí àwọn alátakò ba. Àwọn arẹ́nijẹ ń ṣe èyí nípa gbíngbin ẹ̀rù sí àwọn alátakò lọ́kàn. Nígbà mìíràn wọ́n lè dójútì wọ́n ní gbangba tàbí kí wọ́n tàbùkù àwọn mẹ̀kúnnù láti fi pa wọ́n lẹ́nu mọ́. Gẹ́gẹ́ bí àpẹẹrẹ, arẹ́nijẹ lè lò èrò àwùjọ pé bí a ti bí ẹrú ni a bí ọmọ àti pé ń ṣe ló yẹ kí gbogbo èniyàn máa foríbalẹ̀ fún àwọn aláṣẹ láìtako àgbékalẹ̀ wọn. Nípa èyí, kò ní lè sí àtakò láti ọ̀dọ̀

mẹ̀kúnnù nitori wọ́n ti gba kádàrá tàbí ohun tí ó ń ṣẹlẹ̀ sí wọn bí àyànmọ́ oníkálùkù. Ìgbésẹ̀ yìí ni Althussser pè ní 'Ideological State Apparatus' (ISA) (Ohun èlò ìjẹgàba ajẹmọ́ èrò àwùjọ). Ẹ̀sìn, ìgbàgbọ́ àwùjọ, àṣà, orin, abbl jẹ́ àpẹẹrẹ èròjà ìjẹgàba yìí.

Bí a bá wo àwọn ìgbésẹ̀ yìí, lóòótọ́ ó jẹ́ irinṣẹ́ tí àwọn arẹ́nijẹ máa ń lò láti tẹ orí mẹ̀kúnnù ba gẹ́gẹ́ bí ó ti fara hàn nínú àṣàyàn àwọn ìwé fún iṣẹ́ yìí, ṣùgbọ́n lọ́pọ̀ ìgbà tí ara bá ti ni mẹ̀kúnnù ju bó ti ṣe yẹ lọ, ṣe ni wọn yóò wá ọ̀nà ìjìjàgbara kúrò lọ́wọ́ amúnisìn ní gbogbo ọ̀nà.

## Lítíréṣọ̀ àti Àwùjọ

Èso àwùjọ ni lítíréṣọ̀ jẹ́, bí ìgbín fà, ìkarahun a tẹ̀lé ni pẹ̀lú. Bámidélé (2000: 28) sọ pé:

> Like a prophet or a seer, the artist thinks he has a vision above that of ordinary man to be able to foresee how the star of the course of the ship of the state would run.
>
> Gẹ́gẹ́ bí i wòlíì tàbí aríran, onísẹ́-ọnà lérò pé òun ríran ju ènìyàn lásán lọ débi pé wọ́n lè ti mọ bí ó ti yẹ kí ìṣèlú àwùjọ kan ṣe yẹ kó rí.

Nínú ohun tó ń lọ ní àwùjọ ni ìrẹ́jẹ, ìjẹgàba, owó ẹ̀yìn gbígbà, olè, ìkówó-ìlú-mì, ìgbénipa, ìpànìyàn, ìjínigbé-gbowó, abbl wà. Gbogbo ìwọ̀nyí sì ni lítílésọ̀ ń ya àwòrán rẹ̀ síta yálà nínú ewì, ìtàn àròsọ tàbí eré onítàn bí irú èyí tí isẹ́ yìí dá lé. Onísẹ́ ọnà kìí fojú fo àwùjọ rẹ̀ rárá. Akínyẹmí (2001: 23) fara mọ́ èyí nígbà tó sọ pé:

> No serious African artist ignores the big social and political issue of his contemporary society in his work of art.

> Kò sí oníṣẹ́-ọnà adúláwọ̀ tí ó dágunlá sí ìṣẹ̀lẹ̀ àwùjọ àti ọ̀rọ̀ ìṣèlú tó ń wáyé ní àwùjọ rẹ̀.

Níwọ̀n ìgbà tó jẹ́ pé ará àwùjọ ni òǹkọ̀wé àti pé gbogbo èròjà fún iṣẹ́ rẹ̀ ló pé sí àwùjọ náà, oníṣẹ́-ọnà yòówù kò lè káwọ́ gbera, ìṣẹ̀lẹ̀ àwùjọ gbọ́dọ̀ jẹ wọ́n lógún. Ó sì tún gbọ́dọ̀ farahàn nínú àgbéjáde iṣẹ́ wọn pé ohun tó jẹ lítíréṣọ̀ lógún ni ẹ̀dá ọmọnìyàn àti àwùjọ rẹ̀ (Bámidelé 2000:4). Síwájú sí i, Ògúnṣínà (2006:6) náà sọ pé:

> Literature seeks to investigate man, his behavior in the society…
>
> Lítíréṣọ̀ máa ń ṣàyẹ̀wò ẹ̀dá, ìhùwàsí rẹ̀ ni àwùjọ…

Ọ̀nà tí lítíréṣọ̀ ń gbà ṣàyẹ̀wò ẹ̀dá náà ló fara hàn nínú àwọn ìwé tí a ṣàyẹ̀wò pé lára ìhùwàsí ẹ̀dá ni ìrẹ́nijẹ tó ń wáyé lemọ́lemọ́ ní àwùjọ wa tó sì nílò àkíyèsí.

Ní àkótán, a lè sọ pé lítíréṣọ̀, gẹ́gẹ́ bí èso àwùjọ, ń ṣí wa níyè, ó ń tọ́ ni sọ́nà kò sì jẹ́ kí etí wa di nípa pípolongo àwọn ohun tó ń ṣẹlẹ̀ láwùjọ wa, ó ń tan ìmọ́lẹ̀ sí i lọ́kan-ò-jọ̀kan ọ̀nà.

## Àwùjọ Bí Onípelejìpele

Gẹ́gẹ́ bí òwe àwọn àgbà pé ìka ò dọ́gba, bẹ́ẹ̀ náà ló rí ní àwùjọ kọ̀ọ̀kan níbi tí a ti rí àwọn ènìyàn ní ìsọ̀rí-ìsọ̀rí láti fi ààyè oníkálùkù hàn. Ipò tí ènìyàn bá wà ní àwùjọ rẹ̀ ni yóò fi bí irú ẹni bẹ́ẹ̀ ṣe rí hàn.

Onigu àti Ogionwo (2006: 218) sọ nípa èyí pé:

> Individual in all human societies are not equal and can never be equal.

> Ẹdá ènìyàn ní àwùjọ kọ̀ọ̀kan kò dọ́gba àti pé wọn kò sì le è dọ́gba.

Òótọ́ ọ̀rọ̀ bí ìsọkúsọ ni. Bí a bá wo àwùjọ yòówù, a ó rí pé ìka ò dọ́gba pàápàá àwùjọ tó bá ti jẹ́ kélégbẹ́mẹgbẹ́ níbi tí a ti rí olówó àti mẹ̀kúnnù. Kódà ó tún hàn gbangba pé:

> Inequalities are a product of every human society. There is no human society where indivuals are equal.
>
> (Onigu àti Ogionwo, 2006:218)
>
> Àìbáradọ́gba jẹ́ èso àwùjọ ọmọnìyàn kò sí àwùjọ tí ẹ̀dá ọmọnìyàn ti wà ní dọ́gbandọ́gba.

Adédiméjì (2001) ṣàlàyé pé lára àwọn àbùdá tó lè fi ipò tí ènìyàn yóò wà ní àwùjọ kẹ́lẹ́gbẹ́mẹgbẹ́ hàn ni níní ọrọ̀, agbára, àti ipò àṣẹ; níní ohun àlùmọ́nì jáǹtìrẹrẹ; níní owó lọ́wọ́, iṣẹ́ tó ń ṣe, bí onítọ̀hún ti ṣe lu àlùyọ tó, àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ. Ó fi kún un pé ohun tí àwùjọ bá kà sí pàtàkì ni yóò fi ipò tàbí ààyè oníkálukú hàn. Ọnàbánjọ (2011) naa tún ṣàlàyé pé ń ṣe ni a pín ẹ̀dá ènìyàn sí ipò kọ̀ọ̀kan ní àwùjọ rẹ̀. Ipò yìí ló fi olówó àti mẹ̀kúnnù hàn. Bí a bá sì wò ó, àwọn ọ̀wọ́ tí kò rọ́wọ́ họrí tó bẹ́ẹ̀, ìyẹn àwọn mẹ̀kúnnù, ni olówó yóò máa lò láti mú kí ọ̀rọ̀ wọn pọ̀ síi.

Síwájú sí i, Erinosho (2005) náà ṣàlàyé pé ipò tàbí ààyè tí ènìyàn bá wà ni yóò sọ ìhùwàsí rẹ̀ ní àwùjọ onítọ̀hún.

Nítorí náà, gbogbo àkíyèsí yìí ló fi hàn pé àgbékalẹ̀ àwùjọ kọ̀ọ̀kan ló yàtọ̀ sí ara àti pé ìka kò dọ́gba. Àgbékalẹ̀ àwùjọ kọ̀ọ̀kan ló fi ààyè oníkálùkù hàn àti ibi tí agbára rẹ̀ mọ. Ṣùgbọ́n o, àwùjọ tí àwọn ọ̀wọ́ péréte bá ti ń jẹ gàba lórí àwọn ènìyàn yòókù, tí wọ́n ń fi ọwọ́ ọlá gbá wọn lójú, tí wọ́n ń rẹ́ àwọn

ènìyàn jẹ bó ti ṣe wù wọ́n; kò sí ìgbà tí gbọ́nmi-síi-omi-ò-tóo tàbí ìtàpórógan kò ní máa wáyé.

**Kí ni Ìrẹ́nijẹ?**

Ìrẹ́nijẹ ni gbígbé ẹsẹ̀ lé ẹ̀tọ́ ọmọnìyàn tàbí fífi ẹ̀tọ́ ènìyàn dùn ún láìyẹ. Ó tún lè túmọ̀ sí fífi ohun tó yẹ ènìyàn lá a lójú láìjẹ́ kó tó o lọ́wọ́. Ìrẹ́nijẹ dà bí ìfọwọ́ ọlá gbá ni lójú. A tún lè rí ìrẹ́nijẹ bí ọ̀na tí à ń gbà pa ènìyàn lápasáyé tàbí ṣáyé díẹ̀díẹ̀ lọ́nà tí ayé yóò fi sú onítọ̀hún. Ó tún lè túmọ̀ sí pípani láìyọ idà. Pẹ̀lú gbogbo èyí, a wá lè rí arẹ́nijẹ gẹ́gẹ́ bí ẹni tó ń lo àwọn ọ̀nà ìrẹ́jẹ tí a sọ sókè yìí láti máa fi ayé ni mẹ̀kúnnù lára. Àwọn arẹ́nijẹ ò lójú àánú, á fi òògùn olóòógùn sanra ni wọ́n. Owó tàbí èrè tí arẹ́nijẹ ń rí lára mẹ̀kúnnù jẹ ẹ́ lógún ju ẹ̀mí mẹ̀kúnnù lọ. Arẹ́nijẹ náà ni a tún lè rí bí ẹni tó wà nípò láti ran mẹ̀kúnnù lọ́wọ́, ṣùgbọ́n tí ó dé fìlà ‘má wobẹ̀’. Apanilẹ́kún jayé ni àwọn arẹ́nijẹ, ọ̀-jálé-onílé-bo-tiẹ̀, aríjẹ nínú màdàrú ni wọ́n, àwòdì jẹun èpè sanra, a-fẹ́-ká-jẹ-má-fẹ́-ká-yó rárá ni wọ́n.

Èyí fi arẹ́nijẹ hàn bí ẹni tó ní ọ̀rọ̀ tó pọ̀ tó tún ń lò ó lọ́nà tí ọ̀rọ̀ náà yóò tún fi máa pọ̀ sí i. Ó di dandan pé àwọn mẹ̀kúnnù ni yóò máa lò fún èyí. Láwúwo nínú *Rẹ́rẹ́ rún* náà mẹ́nu ba irú ẹ̀dá tí àwọn arẹ́nijẹ jẹ́ nígbà tó sọ pé:

> ...àwọn ológún ilé, ọlọ́gbọ̀n ọkọ̀, ẹlẹ́gbẹ̀rún aṣọ ìbora...àwọn tí wọ́n jẹ tó, tí wọ́n jẹ ṣẹ́kù tí ọ̀rá fẹ́rẹ̀ lè máa kán sò-sò-sò lára wọn. ...Àwọn aṣánilọ́gbẹ́ abẹ́nú, àwọn alọ́nilọ́wọ́gbà, àwọn afúnnigbẹ àwọn ajẹnirun...
>
> (Òkédìjí, 1973: 29)

Àwọn ológún ilé, ọlọ́gbọ̀n ọkọ̀, ẹlẹ́gbẹ̀rún aṣọ ìbora ni a lè rí bíi àwọn tó ní ànító àti àníṣẹ́kù níbi tí ọ̀gọ̀ọ̀rọ̀ àwọn ènìyàn

ti ń pariwo ìnira. Nígbà tí owó pọ̀ kọjá sísọ ni àwọn arẹ́nijẹ ń kọlé káàkiri bí ẹyẹ níbi tí ó ti ṣòro fún mẹ̀kúnnù láti kọ́ ilé ẹyọ kan ṣoṣo fúnra wọn. kì í ṣe bẹ́ẹ̀ nìkan, àti rówó ilé tí wọ́n ń yáá gbé san tún nira fún wọn pẹ̀lú. Ọlọ́gbọ̀n ọkọ̀ ni a tún lè rí bíi èyí tó ń fi ìgbé ayé rẹ̀ ba mẹ̀kúnnù nínú jẹ́. Nígbà tí owó bá ti pọ̀ lápọ̀jù, tí kò sí ìfẹ́ mẹ̀kúnnù lọ́kàn, dandan ni kí àwọn arẹ́nijẹ máa kó ọkọ̀ ayọ́kẹ́lẹ́ jọ nínú òógùn mẹ̀kúnnù àti láti sọ fún àwọn mẹ̀kúnnù pé ayé dùn ún jẹ ju ìyà tí àwọn mẹ̀kúnnù ń jẹ lọ. Ṣé níbi tí mẹ̀kúnnù kò tíì rọ́wọ́ họrí jẹun kánú ni yóò ti ronú àti ní ọkọ̀ ayọ́kẹ́lẹ́. Ọ̀rọ̀ mẹ̀kúnnù wá di ẹsẹ̀ yá ju mọ́tò, ara ló ń fi àbọ̀ sí. Ẹlẹ́gbẹ̀rún aṣọ ìbora fi àwọn arẹ́nijẹ hàn bí ẹni tí ń pààrọ̀ aṣọ bí ọ̀gà. Èyí fi arẹ́nijẹ hàn bí ẹni tó máa ń ṣàṣejù níbi tí ó ti ṣòro fún mẹ̀kúnnu láti rí aṣọ kan bora tàbí tí ọ̀rọ̀ di ogun di ọdẹ kí mẹ̀kúnnù tó lè rí aṣọ dà bora. Ọ̀gọ̀ọ̀rọ̀ àwọn mẹ̀kúnnù ló ń fi abẹ́rẹ́ gán aṣọ wọn.

Jíjẹ tó àti jíjẹ ṣẹ́kù fi arẹ́nijẹ hàn bí ẹni tó ní owó yanturu, tí àtijẹ àtimu dẹ̀ lọ́rùn, níbi tí àwọn mẹ̀kúnnù ti rù han-n-gogo, tí àti rí oúnjẹ ẹ̀ẹ̀kan jẹ lójúmọ́ ti jẹ́ ìnira. Ṣé níbi tí mẹ̀kúnnù kò ti jẹ àjẹyó ni yóò ti jẹ àjẹṣẹ́kù? Asánilọ́gbẹ́ abẹ́nú ni a lè rí bí oríṣìíríṣìí ọgbọ́n tí àwọn arẹ́nijẹ ń mú lò láti máa fi ayé ni àwọn mẹ̀kúnnù lára. Lílọ́nilọ́wọ́gbà ni a lè rí bí oríṣìíríṣìí ìgbésẹ̀ àwọn arẹ́nijẹ níbi tí wọ́n ti ń fi tipátipá gba ohun tí àwọn mẹ̀kúnnù ìbá fi máa ṣayé lọ́wọ́ ọ wọn, èyí tó fi àwọn arẹ́nijẹ hàn bí agbàlọ́wọ́mérìí.

Bí a bá wo gbogbo àkíyèsí yìí, ń ṣe ló ṣe régí pẹ̀lú irú ẹni tí arẹ́nijẹ ń ṣe gẹ́gẹ́ bí èròǹgbà Awonuga (1988: 157) sọ pé “Capitalism is characterised by greed, selfishness, theft and wickedness” (àbùdá arẹ́nijẹ jẹ́ èyí tó kún fún ìwà ojúkòkòrò,

ìmọtara-ẹni-nìkan, olè àti ìwà ìkà) tí ó túmọ̀ sí pé orísìírísìí ìwà tó fi bí àwọn arẹ́nijẹ ṣe burú tó ni ó fara hàn yìí.

Adélékè sọ nípa ìrẹ́nijẹ pé:

> Ọjọ́ ti pẹ́ tí kóówá ẹ̀dá èniyàn ti ń lo agbára yálà láti tẹ́ àníyàn ara ẹni lọ́rùn tàbí láti fi ipò ẹni hàn. Káríayé ni ọ̀rọ̀ yìí.
>
> (Adélékè, 2005: 17)

Èyí túmọ̀ sí pé kì í ṣe pé à ń rẹ́nijẹ ṣẹ̀ṣẹ̀ bẹ̀rẹ̀ ni àwùjọ wa ni, ń ṣe ló tún ń dàgbàà sí i ló yẹ ká sọ. Láti fi hàn pé ọjọ́ ti pẹ́, tí a bá wo inú Bibeli àwọn ọmọlẹ́yìn Kírísítì, a lè tọ́ka sí díẹ̀ lára ìwà ìrẹ́nijẹ tàbí fífi agbára hàn lórí ẹni èyí tó fara hàn níbẹ̀. Bí àpẹẹrẹ, Ọba Dáfídì lo ipò àti agbára rẹ̀ láti gba Bátíṣẹ́bà ìyàwó Ùríà tí ó jẹ́ jagunjagun fún Dáfídì. Kì í ṣe bẹ́ẹ̀ nìkan, nígbà tí Ọba Dáfídì rí i pé àṣírí yìí fẹ́ tú síta, kíá ló ṣètò tí Ùríà fi gba ọ̀run alákeji lọ. Lẹ́yìn èyí ni Ọba Dáfídì kúkú sọ Bátíṣẹ́bà di aya rẹ̀ (2 Samueli 11:1-27). bí a bá wò ó dáradára, ojú kò ti Ọba Dáfídì láti fẹ́ ìyàwó ọmọ abẹ́ẹ rẹ̀, kò tún ni Dáfídì lára láti pa ọkọ ìránṣẹ́bìnrin yìí. Fífi ọwọ́ ọlá gbáni lójú ni a lè rí èyí sí gẹ́gẹ́ bí ara àbùdá arẹ́nijẹ.

Lọ́nà mìíràn, Ọba Áhábù ń fẹ́ ọgbà àjàrà Nábótì, tí onítọ̀ún sì kọ̀ fún un. Bí ìyàwó rẹ̀ ṣe gbọ́ èyí ló ṣètò kíákíá lọ́nà àti yanjú ẹni tó ni ọgbà àjàrà náà. Lẹ́yìn èyí ni ọgbà àjàrà Nábótì di ti Ọba Áhábù (I Awọn Ọba 21:1-16). Bí a bá wò ó, nǹkan àwọn arẹ́nijẹ kì í tó wọn, bí i kí gbogbo ayé ó jẹ́ tiwọn ni.

Nítorí náà, ìrẹ́nijẹ dà bí ìmúnisìn. Gbogbo àwọn àpẹẹrẹ yìí ń fi hàn pé ọjọ́ ti pẹ́ tí arẹ́nijẹ ti wà ní àwùjọ wa pẹ̀lú ọ̀nà ìrẹ́nijẹ orísìírísìí.

## Ìhùwàsí àwọn arẹ́nijẹ nínú àwọn àṣàyàn ìwé eré-onítàn Yorùbá

Ọwọ́ àwọn arẹ́nijẹ ni ìwà ìninilára pin sí. Bí àpẹẹrẹ, Onímògún sọ fún àwọn òṣìṣẹ́ tó ń béèrè ẹ̀kúnwó pé:

> ...Láti òní lọ...kò sí ẹ̀kúnwó kankan mọ́ fún òṣìṣẹ́ kankan fún ọdún méjì gbáko.
>
> (Òkédìjí, 1973:17)

Bí kò bá sí ẹ̀kúnwó fún ọdún méjì gbáko, báwo ni yóò ti ṣe burú tó fún àwọn òṣìṣẹ́ tó ní bùkátà lọ́kan-ò-jọ̀kan? Nígbà tí ẹ̀kúnwó wà, nǹkan kò ṣe bẹ́ẹ̀ ṣenuure fún àwọn òṣìṣẹ́, báwo ni ìnira yìí yóò ṣe tó láàrin ọdún méjì níbi tí kò ti sí pé èlé ń gun orí owó oṣù?

Ní àfikún, Onímògún tún ṣe ìpàdé pẹ̀lú àwọn ìgbìmọ̀ rẹ̀. Àbayọrí ìpàdé yìí kò so èso rere fún àwọn òṣìṣẹ́.

> Ìgbìmọ̀ pinnu pé gẹ́gẹ́ bí ipò tí ilé ìṣura ìlú wà báyìí, a ó yọ náírà mẹ́jọ-mẹ́jọ kúrò nínú owó oṣù òṣìṣẹ́ kọ̀ọ̀kan... A fi náírà méjì-méjì kún owó orí ẹnìkọ̀ọ̀kan...iṣẹ́ yóò máa bẹ̀rẹ̀ ní aago mẹ́fà òwúrọ̀, ẹ ó sì máa síwọ́ ní aago méje àṣáálẹ́.
>
> (Òkédìjí, 1973: 72)

Dídá àfikún owó oṣù dúró fún ọdún méjì kò tíì tó, ń ṣe ni ìgbésẹ̀ tún wá láti tún máa yọ nínú owó tí kò tíì tó gbọ́ bùkààtá tẹ̀lẹ̀. Àfikún àkókò tí àwọn òṣìṣẹ́ yóò máa wà lẹ́nu iṣẹ́ àti fífi kún owó orí tí àwọn òsìṣẹ́ yóò máa san jẹ́ ìnira ńlá fún àwọn òsìṣẹ́.

Kò dúró síbẹ̀, irú ìwà ininilára yìí náà hàn nínú ìṣèjọba Ọba Adékànmbí nínú *Orí Mẹ̀kúnnù* nípa fífi ara ni aráàlú lẹ́yìn tí ipò Ọba ti bọ́ sí i lọ́wọ́ tán. Ó ní:

> ...Lẹ́yìn tí èmi àti àwọn ìjòyè mi ti rò ó síwá, tí a sì ti rò ó sẹ́yìn, a wá ríi pé ó pọn dandan láti fi kún owó orí tí ẹ̀ ń san. Nígbà ti a ro bí òde ṣe rí àti bí kò ti ṣe sí owó nígboro, náírà mẹ́wàá ni a fi kún mẹ́wàá

> tí ẹ̀ ń san tẹ́lẹ̀. Nítorí náà, obìnrin yóò bẹ̀rẹ̀ owó orí náírà mẹ́wàá péré ní sísan. Yàtọ̀ sí èyí, kí ọdún tó parí, a fẹ́ ṣe ètò ìkówójọ fún ìdàgbàsókè ìlú wa yìí... Nítorí náà, ọkùnrin kọ̀ọ̀kan yóò dá ogójì náírà, obìnrin kọ̀ọ̀kan yóò da ogún náírà péré.
>
> (Fánílọlá, 1991: 48)

Nínú ọ̀rọ̀ Ọba Adékànmbí, òun fúnra rẹ̀ mọ̀ pé nǹkan kò dẹrùn fún àwọn ènìyàn, síbẹ̀ ó tún fẹ́ ni àwọn ènìyàn lára nípa ṣíṣe àfikún owó orí àti ìkówójọ tipátipá fún àwọn ènìyàn. Àkíyèsí ni pé nínú ìkówójọ yòówù, ń ṣe ni olúkúlùkú máa ń ṣe bí agbára bá ti mọ, ṣùgbọ́n ń ṣe ni Ọba tìkalára rẹ̀ bu iye tó wù ú fún àwọn ènìyàn ìlú.

Irú ìwà yìí náà wà nínú ìṣesi Adédùn tíí ṣe Olorì Ọba Ṣiyanbọ̀lá. Lórí ìsọ̀-ọjà tó jẹ́ pé ń ṣe ni àwọn kan ń pín mọ́wọ́, ohun tí Olorì Adédùn náà ń sọ ni pé:

> Ó dára, irú ìsọ̀ ọjà tí wọ́n ń pín yẹn, ṣé kò yẹ kí èmi ó ní bí i àádọ́ta níbẹ̀, kí n sì wá há a fún àwọn tó bá wù mí ní èléwó
>
> (Ìṣọ̀lá, 2009: 35)

Ọ̀tọ̀ọ̀tọ̀ ayaba lèyí tí òun náà kò gbèrò ìdẹ̀rùn fún àwọn aráàlú àfi bí yóò ti ni wọ́n lára.

Àkíyèsí lórí èyí ni pé tí ìrẹjẹ bá dé góńgó, ìtápórógan àti ìjìjàgbara àwọn mẹ̀kúnnù ló kù. Bí kò bá rí bẹ́ẹ̀, bóyá ni àwọn mẹ̀kúnnù lè gba ara wọn lọ́wọ́ ìjọba arẹ́nijẹ.

Abájọ tí Berker (1946: 217) náà ṣe sọ pé:

> Revolutions are due partly to the unjust treatment of the masses.
>
> Ìjìjàgbara máa ń wáyé láti ipasẹ̀ fífi ìyà tí kò lẹ́tọ̀ọ́ jẹ àwọn ènìyàn.

Lọ́nà mìíràn, àwọn aláṣẹ máa ń wá ọ̀nà láti fa àwọn èniyàn bọ̀dí nípa wíwá ojú wọn mọ́ra, pàápàá àwọn tó bá jẹ́ alátakò sí ìṣèjọba wọn tàbí abẹnugan àwọn mẹ̀kúnnù. A rí àpẹẹrẹ yìí nínú ọ̀rọ̀ tó súyọ nínú ìpàdé tí Onímògún àti àwọn ìgbìmọ̀ rẹ̀ bá Láwúwo ṣe. Olúgbọ́n ní:

> Kàká kí o máa dààmú ìgbìmọ̀ ìwọ ó ṣe kúkú da ara rẹ̀ pọ̀ pẹ̀lú mọ́ àwọn ìgbìmọ̀ kí o sì sọ ohun tí o bá ń fẹ́ kí ìgbìmọ̀ ṣe fún ọ
>
> (Òkédìjí, 1973:44)

Ohun tí àwọn ìgbìmọ̀ ń fẹ́ ni kí wọ́n fa Láwúwo bọ̀dí, kí ó di ara àwọn arẹ́nijẹ, kí wọ́n tẹ́ ẹ lọ́rùn, kí ààyè lè ṣí sílẹ̀ láti ṣe àwọn òṣìṣẹ́ bó ṣe wù wọ́n.

Síwájú sí i, a tún lè rí àbùdá ọmọ iná làá rán síná nínú ìhùwàsí àwọn arẹ́nijẹ. Bí ọ̀rọ̀ bá fẹ́ẹ̀ díjú, tí ó jọ pé àwọn arẹ́nijẹ kò tíì rí ààyè pa itú ọwọ́ ọ wọn lórí mẹ̀kúnnù, ń ṣe ni wọn máa ń lo àwọn èniyàn tàbí ẹgbẹ́ sí ara wọn. A rí àpẹẹrẹ yìí nínú *Rẹ́rẹ̀ Rún* gẹ́gẹ́ bí ó ti hàn nínú ọ̀rọ̀ Arẹ̀ṣà pé:

> Ẹ̀yin lẹ̀ ń fa ọ̀rọ̀ gùn. Èyí tí a ti patì un là bá tẹra mọ́. Ká dẹ wọ́n síraa wọn. Ká dẹ Ìdòwú sí Láwúwo, ká dẹ àwọn òṣìṣẹ́ mìíràn síi pẹ̀lú.
>
> (Òkédìjí, 1973: 51)

Bí a bá ṣe àkíyèsí ọ̀rọ̀ yìí, Ìdòwú wà lára ọmọ ẹgbẹ́ òṣìṣẹ́ tó ń bá wọn ṣe wọlé wọ̀de nínú ìpàdé gbogbo. Ṣé Yorùbá bọ̀, wọ́n ní ọmọ iná làá rán síná, èrò àwọn arẹ́nijẹ ni pé Ìdòwú tó jẹ́ ọmọ ẹgbẹ́ ló lè mọ ọ̀nà àti mú Láwúwo. Lóòótọ́ wọ́n gbé ìgbésẹ̀ bẹ́ẹ̀ ó sì ṣiṣẹ́ fún wọn, ìgbésẹ̀ yìí ló fa ikú Mọrẹ́nikẹ́ ìyàwó Láwúwo, tí orí Láwúwo náà sì dàrú. Kì í ṣe bẹ́ẹ̀ nìkan, àwọn ọmọ ẹgbẹ́ òṣìṣẹ́ kò leè tẹ̀síwájú mọ́ nínú ìjìjàgbara wọn nítorí adarí tuntun tí àwọn aláṣẹ yàn fún wọn.

Bí a bá wo àwùjọ wa bákan náà, a máa ń rí i pé lọ́pọ̀ ìgbà, àwọn adarí a máa lo àwọn ọmọ ẹgbẹ́ láti da àárin ẹgbẹ́ bẹ́ẹ̀ rú. Èrò àwọn arẹ́nijẹ ni pé tí wọ́n bá ti da àárin wọn rú, kíá ni ọ̀rọ̀ wọn yóò tako ara, tí àwọn arẹ́nijẹ yóò sì ráàyè pitú ọwọ́ wọn. Irú ìgbésẹ̀ yìí a máa wáyé láàrin ìjọba àti àwọn ẹgbẹ́ òṣìṣẹ́ pàápàá ní àkókò ìyanṣẹ́lódì.

Àbùdá mìíràn ni ìmọ̀tara-ẹni, nǹkan tíwọn nìkan ló máa ń ká àwọn aláṣẹ lára. Bí àpẹẹrẹ, àga tí wọn yóò rà fún Onímògún ṣe pàtàkì ju owó oṣù àwọn òṣìṣẹ́ lọ. Nígbà tí akọ̀wé àgbà rán ọba létí nípa àìtíì san owó oṣù àwọn òṣìṣẹ́ fún oṣù tó kọja, esì tí Onímògún fọ̀ ni pé:

> Nítorí náà ń kọ́? Ọjọ́ wo loṣù parí ná?
>
> (Òkédìjí, 1973:20)

Èyí ṣàfihàn pé sísan owó oṣù òṣìṣẹ́ ní àkókò tó yẹ kò sí lójú ìwé Onímògún. Bí kì í bá ṣe bẹ́ẹ̀, ko yẹ kí Onímògún gbàgbé pé tí oṣù bá ti parí ló yẹ kí àwọn òṣìṣẹ́ tẹ́wọ́ gbowó wọn. Ní orílẹ̀-ède wa lónìí, àìsanwó oṣù fún àwọn òsìṣẹ́ ti di àǹkóò fún àwọn Gòmínà gbogbo káàkiri Ìpínlẹ̀. Bẹ́ẹ̀ náà ni a ṣì rí àwọn ọ̀gá ilé-iṣẹ́ lọ́pọ̀ yanturu tí wọ́n ń fi owó oṣù jẹ àwọn òsìṣẹ́ wọn níyà.

Lọ́nà mìíràn, àti ṣe àánú máa ń nira fún àwọn arẹ́nijẹ. Kàkà kí àánú àwọn òṣìṣẹ́ ìbá fi ṣe Olúgbọ́n, ń ṣe ló tún ń fínná mọ́ wọn. Èyí hàn nínú ọ̀rọ̀ rẹ̀ nígbà tó sọ pé:

> Owó oṣù àwọn òṣìṣẹ́ ló ṣe pàtàkì jù ni àbí owó ọba ìlú wa? Bí kò bá sí ìjòyè, ta ni ọ̀sìṣẹ́ ó gba owó oṣù lọ́wọ́ rè?
>
> (Òkédìjí, 1973:26)

Olúgbọ́n ti gbàgbé pé tí kò bá sí ará ìlú, lára àwọn tí a ti rí òṣìṣẹ́, ta ni Ọba yóò ṣèlú lé lórí?

Bákan náà, ìṣesí àwọn arẹ́nijẹ ni pé bí alátakò kò bá gbà lẹ́rọ̀ ó gbọ́dọ̀ gbà pẹ̀lú tipátipá. Nígbà tí àwọn ìgbìmọ̀ fẹ́ ṣe ìpàdé pẹ̀lú Láwúwo bí wọn yóò ti ṣe fa ojú rẹ̀ mọ́ra. Ohun tí ó wà lọ́kàn Arẹ̀ṣà sí Láwúwo ni pé:

> Bí ò bá gbà, àgbàwọlẹ̀ la á gba a.
>
> (Òkédìjí, 1973:43)

Ohun tí èyí túmọ̀ sí ni pé bí Láwúwo bá fi lè kọ gbogbo ìgbéṣẹ̀ láti tù ú lójú, ohun tí ojú Láwúwo yóò rí níkẹ̀yìn yóò burú jọjọ. Bí a bá sì wo ohun tó ṣẹlẹ̀ sí Láwúwo nígbẹ̀yìn, àgbáwọlẹ̀ ni wọ́n gbá a nítòótọ́ nígbà tí ó kọ àbẹ̀tẹ́lẹ̀ àwọn arẹ́nijẹ.

Ní ọ̀nà mìíràn, A-jí-edé-jẹ kì í jẹ ọ̀kan kó síwọ́ lọ́rọ̀ àwọn arẹ́nijẹ. Èyí túmọ̀ sí pé òùngbẹ rírẹ́ àwọn mẹ̀kúnnù jẹ ló máa ń gbẹ wọ́n. Láti jẹ́rìí sí èyí, Àyàn ṣàfihàn Ọba Ṣiyanbọ́lá nínú *Ayé Yẹ Wọ́n Tán,* ó ní:

> Ṣiyanbọ́lá fiyà jẹ mí púpọ̀ ní tèmi. Gbogbo owó tọ́ba ní láti fún onílù kò fún mi...
>
> (Ìṣọ̀lá, 2009: 164)

Èyí túmọ̀ sí pé àwọn arẹ́nijẹ kúndùn láti máa lo àwọn ènìyàn ní ìlò omi òjò láìfún wọn ní ẹ̀tọ́ wọn rárá. Orúkọ wọn a máa rò wọ́n nínú ìṣesí wọn.

Kò pin síbẹ̀, Àyànlọlá tún fi ìwà àwọn arẹ́nijẹ yìí hàn síwájú pé:

> ...Èyí tó wà dùn mí jù ni ti ilẹ̀ mi gan-an. Wọ́n sì wá pín-in mọ́wọ́ tán, wọn ò tilẹ̀ wá mẹ́nu ba tèmi mọ́. Bí ìjọba bá gbalẹ̀, ṣebí ó yẹ kí wọn ó sanwó? ...Àní èmi ni mo tún lù níbi tó ti ń sílé tí wọ́n kọ́ sórí ilẹ̀ baba mi láìgba kọ́bọ̀. Ṣiyanbọ́lá ti gba gbogbo owó ilẹ̀ sápò.
>
> (Ìṣọ̀lá, 2009: 164)

A rí ìwà yìí bí ẹni tó jálé onílé bo tiẹ̀ mọ́lẹ̀, fífi ọwọ́ ọlá gbá ni lójú àti yíyannijẹ ká tún fi hàn ènìyàn. Ṣé irú Ọba ló yẹ kó ra ilẹ̀

kó má san owó? Kó tún jẹ́ pé ẹni tí ọba gba ilẹ̀ lọ́wọ́ rẹ̀ láìsan owó ni ọba tún pè kó wá lu ìlù fún òun lọ́fẹ̀ẹ́. Gbogbo owó ilẹ̀ tí Ìjọba tún san, àpo Ọba ló kó sí.

Bẹ́ẹ̀ náà ni irú ìwà yìí tún hàn lára Lísa àti Àró nínú *Orí Mẹ̀kúnnù* tí wọ́n gbé iṣẹ́ ìdàgbàsókè ìlú fún. Ń ṣe ni àwọn méjèèjì lo ipò wọn láti rẹ́ àwọn ará ìlú jẹ. Àpínmọ́wọ́ àti kíkósápò ni wọ́n fi ẹ̀tọ́ ìlú ṣe. Èyí hàn nínú ìwà Àró nígbà tó sọ pé:

> Ṣe bí o mọ̀ pé nínú owó tí ìlú dá láti fi ṣe omi ẹ̀rọ àti iná mọ̀nàmọ́ná ni mo ti yá kọ́ ilé mi òkè ọjà.
>
> (Fánílọlá, 1991:22)

Ìbéèrè ni pé ta ni Olóyè Àró ya owó tó yẹ fún ìdàgbàsókè ìlú lọ́wọ́ọ rẹ̀? Ìgbà wo ni yóò san owó náà padà? Ìwé wo ló fọwọ́ sí pé òun yá owó? Irú owó bẹ́ẹ̀ ti di àjẹmúrá. Ohun tó tún yé wa ni pé ààrín olóyè Àró àti Lísà nìkan ni wọ́n ti ń sọ ọ̀rọ̀ náà àti pé àṣìírí ọ̀rọ̀ náà, ààrín àwọn méjèèjì ló wà. Irú ìwà yìí náà wà lọ́wọ́ Lísà, bákan náà, oùn náà sọ pé:

> Ẹ̀yin gbàgbé pé mo jẹ́ ọ̀kan lára alákòóso ilé-iṣẹ́ tí wọ́n gbé kíkọ́ ilé-ìwòsàn tí a fẹ́ kọ́ fún, Taksí tí mo fi ìdámẹ̀wàá owó tí ó kàn mí rà náà ni olè ti gbé lọ yẹn.
>
> (Fánílọlá, 1991:22)

Ohun tí èyí ṣàfihàn ni pé ọ̀kánjúà ni àwọn arẹ́nijẹ. Wọ́n máa ń lo àǹfààní tó bá sí sílẹ̀ fún wọn láti jẹ kí ohun tí ó bá tọ́ sí gbogbo ará ìlú di tiwọn nìkan.

Bẹ́ẹ̀ náà lọ̀rọ̀ rí nínú *Ayé Yẹ Wọ́n Tán* níbi tí ojúkòkòrò àti ìfẹ́ owó ti fara hàn. Gẹ́gẹ́ bí ẹ̀rí, nítorí ìdámẹ̀wàà ti Ọba Ṣiyanbọ́lá àti àwọn ìjòyè rẹ̀ yóò rí nínú iṣẹ́ tí wọ́n bá gbé fún agbaṣẹ́ṣe ni wọ́n kó fi jẹ́ kí ẹgbẹ́ alájọ̀ṣe ṣe iṣẹ́ náà ni ẹ̀dínwó. Èyí náà hàn nínú ọ̀rọ̀ Ọba Ṣiyanbọ̀lá pé:

> ...Awon ẹgbẹ́ alájùmọ̀ṣe yìí ni àwọn fẹ́ẹ́ kọ́ ọ fúnra
> wọn ní ẹ̀dínwó kí ìgbìmọ̀ lè rówó ṣe nǹkan mìíràn.
> Àwa la takú tí a gbé e fún àgbàṣẹ́ṣe lówó gọbọi.
> (Ìṣọ̀lá, 2009: 46)

Lọ́nà mìíràn, ẹnu wọn ní ọ̀rọ̀ aṣa àti kòbákùngbé pín sí. Lẹ́yìn tí Ọba Ṣiyanbọ́lá kọ̀ láti mú ìlérí ṣẹ fún àwọn ẹgbẹ́ alájùmọ̀ṣe, òkò ọ̀rọ̀ ló tún ń sọ sí wọn pé:

> Mẹ̀kúnnù, mẹ̀kúnnù, èmi ni mo sọ ẹnìkan di olòsì
> ni? Àbí mo ní kí ẹni tó bá fẹ́ là kó má là?
> (Ìṣọ̀lá, 2009: 49)

Yorùbá bọ̀ wọ́n ní, ẹni tó bá sọni di olórí burúkú ló kọ́kọ́ ń fi búni, àwọn arẹ́nijẹ náà ló bá mẹ̀kúnnù dé ipò àìdáa tí wọ́n wà. Àfi bí ẹni pé ìyẹn kó tíì tó, ẹ tún gbọ́ èyí:

> n ò rán mẹ̀kúnù nísẹ́
> kí àwọn náà múra kí wọ́n
> kúrò ní ẹgbẹ́ olòṣì.
> (Ìṣọ̀lá, 2009: 51)

Èèpo ẹ̀pà àwọn mẹ̀kúnnù ti di ohun tí àwọn arẹ́nijẹ kì í fẹ́ẹ́ jí rí mọ́. Lójú arẹ́nijẹ, mẹ̀kúnnù ti di ẹgbẹ́ olòṣì. Irú ọ̀rọ̀ apanilẹ́kún, amúnironú lọ́nà òdì àti èyí tó máa ń yẹpẹrẹ mẹ̀kúnnù, inú ìwà àwọn arẹ́nijẹ ló wà.

Àìlòjútí yìí ló mú Àró, Lísà àti Ọ̀dọ̀fin nínú *Orí Mẹ̀kúnnù* gba owó àti ọkọ̀ ayọ́kẹ́lẹ́ tí Adékànmbí fún wọn gẹ́gẹ́ bí owó ẹ̀yìn, kí ipò Ọba lè tó o lọ́wọ́. Èyí ló mú ọ̀rọ̀ rírùn yìí jáde lẹ́yìn tí wọ́n ti gba owó àbẹ̀tẹ́lẹ̀ lọ́wọ́ ẹni tí ipò Ọba kò tọ́ sí pé:

> Lórúkọ mi, Lísà àti Ọ̀dọ̀fin mo bá ẹ yọ̀ Adékànḿbí
> pé o kú oríire náà.
> (Fànílọlá, 1991: 28)

Lára àwọn afọbajẹ ni àwọn tó gba owó ẹ̀yìn yìí wà tí wọ́n sì fi Adékànmbí jọba. Ẹni tí ojú kì í bá á tì wàyí, kò sí ohun tí kò le ṣe.

Gẹ́gẹ́ bí àbùdá, ń ṣe ni wọ́n máa ń fi ẹnu ya ẹran sọ́bẹ̀ fún àwọn ènìyàn lọ́nà àti lè ráàyè máa rẹ́ wọn jẹ lọ. Bí àpẹẹrẹ, Ọba Ṣiyanbọ́lá ló ṣe ìlérí kó tó jọba pé òun yóò bá àwọn ẹgbẹ́ alájúmọ̀ṣe yanjú ilẹ̀ tí wọn yóò kọ́ ilé ẹgbẹ́ sí, ṣùgbọ́n kò mú ìlèrí náà ṣẹ gẹ́gẹ́ bó ti ṣe hàn nínú ọ̀rọ̀ òun tìkalárarẹ̀ pé:

> ...ibi tí a wá fẹ́ lò jẹ́ ara ibi tí mo ti ṣèlérí fún àwọn ẹgbẹ́ yẹn nígbà kan...
>
> (Ìṣọ̀lá, 2009: 50)

Èyí fihàn pé ìlérí ṣíṣe kò jọ wọ́n lójú, kò sì ní ìtumọ̀ gidi sí wọn. Láti ṣe àfikún, Òbí náà jẹ́rìí sí ìwà Ọba Ṣiyanbọ́lá yìí nígbà tó sọ pé:

> Ẹ má fọkàn tán ọkùnrin náà tán o, wọ́n ṣèlérí ẹ̀kúnwó fáwa naa. Àmọ̀ báà bá tíì gbà á báyìí a ò mà lè sọ, ìlérí ahun kò láyọ̀lé,
>
> (Ìṣọ̀lá, 2009: 25)

Èyí fihàn pé ń ṣe ni arẹ́nijẹ máa ń gbé ọkàn àwọn ènìyàn sókè lásán. Abájọ tí ìdaṣẹ́sílẹ̀ oríṣìíríṣìí ṣe máa ń ṣẹlẹ̀ wẹ́lẹ́wẹ́lẹ́ nígbà tí àwọn adarí bá ṣe ìlérí láìbọ̀wọ̀ fún ìlérí náà.

Síwájú síi, àwọn arẹ́nijẹ kò bìkítà láti fi ẹ̀mí ènìyàn ṣòfò, èyí tó túmọ̀ sí pé wọn kò náání ẹ̀mí ènìyàn. Gẹ́gẹ́ bí àwílé, pípa tí àwọn jàǹdùkú pa Ọládépò níbi tí wọ́n ti ń ṣe ìpàdé kò sẹ̀yìn Ọba Ṣiyanbọ́lá, bẹ́ẹ̀ náà ni ikú tó pa Fáṣakin. Lẹ́yìn tí Òní ti fún ọba ní ìròyìn ohun tó ṣẹlẹ̀, Ọba Ṣiyanbọ́lá ní:

> ...ó fi dáa ni, kí Ọlọ́run wo ọmọ rẹ̀. Ẹni tó bá ni kí á má jayé, àjẹmáyé ni o.
>
> (Ìṣọ̀lá, 2009: 89)

Bẹ́ẹ̀ náà ni ọ̀rọ̀ rí nínú *Orí Mẹ̀kúnnù* nípa ìgbésẹ̀ tí Ọba Adékànḿbí gbé nípa yíyanjú àwọn alátakò rẹ̀. Bí ọ̀rọ̀ bá rí báyìí, ó fi hàn pé ẹnikẹ́ni tó bá fẹ dí àwọn arẹ́nijẹ lọ́nà ìjẹ wọn, irú ẹni bẹ́ẹ̀ lè di mímú kúrò láìròtì.

## Àgbálọgbábọ̀

Iṣẹ́ yìí ti ṣàlàyé oríṣìíríṣìí itú tó wà lọ́wọ́ àwọn arẹ́nijẹ gẹ́gẹ́ bi àbùdá wọn tí wọ́n fi ń ṣọṣẹ́ fún àwọn mẹ̀kúnnù. Lára àwọn àbùdá bẹ́ẹ̀ ni ìwà ìninilára, kíkọ ìhà kò-kàn-mí sí ìṣòro aráàlú, ìwà bó-o-bá-a kí-o-pa-á, bí-o-kò-bá-a-kí-o-bù-ú-lẹ́sẹ̀, abbl. Arẹ́nijẹ kan kì í fẹ́ kí mẹ̀kúnnù gbérí lábẹ́ ìṣèjọba wọn, ẹni tí yóò máa sìn wọ́n títí láé ni wọ́n ń wá. Bẹ́ẹ̀ ni inú arẹ́nijẹ kì í dùn sí ìṣerere mẹ̀kúnnù, apanilápasáyé ni wọ́n jẹ́ pẹ̀lú.

Ní àkótán, ìwà ìrẹ́nijẹ kò tíì kásẹ̀ nílẹ̀ láwùjọ wa, ojoojúmọ́ ló ń peléke sí i. Ohun tí ó yẹ kí àwọn ará ìlú mọ̀ ni pé bí òǹdupò òṣèlú kan bá ti ní irú àwọn àbùdá tí à ń tọ́ka wọ̀nyí, bí irú ẹni bẹ́ẹ̀ bá gbé àpótí ìdìbò, kò yẹ kí á dìbò fún irú ẹni bẹ́ẹ̀. Ìdí ni pé tí irú wọn bá ń fi ètè dídùn polongo ìbò, bí wọ́n bá dé ibẹ̀ tán, ìyà à-jẹ-bó-lórí ni wọn yóò máa fi jẹ àwọn mẹ̀kúnnù.

## Ìwé Ìtọ́kasí

Achebe, Chinua (1983). *The Trouble with Nigeria*. Enugu: Fourth Dimension Publishers.

Adédiméjì, A. (2001). “Social Stratification and Social Mobility”. In Shoremi, M.O., Edewor, P.A. and Olutayo, O. (Eds.) *The Science of Society, A Sociological Introduction.* Ìjẹ̀bú-Òde: CESAP Pub.

Adélékè, Dúró (2005). "Ìfagagbága Àwọn Aláṣẹ àti Mẹ̀kúnnù Nínú Fíìmù Ìjà Òmìnira àti Ṣaworo-Idẹ" ní *Láàńgbásà: Jọ̀nà Iṣẹ́ Akadá ní Èdè Yorùbá*, No. 11, o.i. 171-185.

Adétóyè, D. (2014). "Governance and Leadership in Nigeria" In Sociological Issues in Industry and Nigerian Society. Nurudeen Aliyu (Ed.). Ibadan: University Press Plc.

Adéyẹmí, Lérè (2006). *Tíọ̀rì Lítíréṣọ̀ ní Èdè Yorùbá*. Ìjẹ̀bú-Òde: Shebiotimo Publications.

Adéyẹmọ, O.A. (2005). "Ìjìjàgbara nínú Eré-oníṣe Yorùbá", M.A. Thesis, Ọbáfẹ́mi Awólọ́wọ̀ University, Ilé-Ifẹ̀.

Akínyẹmí, A. (2001). "Olú Owólabí's Ọ̀tẹ̀ Nìbò: A Documentary on Nigeria's Political Stability". In Charles Bodunde (Ed.) *African Language and Literature in the Political Context of the 1990s*. Germany: Eckhand Brettinger, Bayreuth University, o.i. 28-38.

Althusser, Louis (1971). "Ideology and Ideological State Apparatuses". *Lenin and Philosophy and Other Essays*. o.i. 121-176.

Àríyọ̀, A. Tobi (2015). "Dilemma of Political Leadership in Nigeria". In *Sociological Issues in Industry and Nigerian Society*. Nurudeen Alliyu (Ed.). Ìbàdàn: Ìbàdàn University Press.

Awónúgà, C.O. (1985). "Political Rhetoric: Awọ́lọ́wọ̀'s use of language" In ODU-Journal of West African Studies. Toyin Falola (Ed.). Ilé-Ifẹ̀: Ọbáfẹ́mi Awọ́lọ́wọ̀ University Press.

Bámidélé, L.O. (2000). *Literature and Sociology.* Ibdan: Stirling Horden Nig. Ltd.

Berker, A. (1946). *The Politics of Aristotle.* Oxford: Clarendon Press.

Bíbélì Yorùbá Atọ́ka (1980). Májẹ̀mú Láéláé àti Májẹ̀mú Tuntun. Kaybal Foundation Limited, Christ Mission Publications.

Bọ́lárìnwá, A.O. (2016). "Exemplification of Political Conflict in Selected Yorùbá Novels" in *Journal of Yorùbá Studies Association of Nigeria.* Vol. 8, No. 2, o.i. 133-159.

Eagleton, T. (1976). *Marxism and Literacy Criticism*. Britain: Richard Clay Ltd.

Erinosho, O.A. (2005). *Sociology for Medical, Nursing and Allied Professions in Nigeria.* Ijebu-Ode: Bukrark Consult.

Fánilọ́lá, K. (1991). *Orí Mẹ̀kúnnù*. Ìbàdàn: Royal Printers Industries Ltd.

Gbàdàmọ́sí, O.O. (2003). "Dùndún Ensemble in Ọ̀yọ́", Unpublished M.A. Project, Department of Linguistics and African Languages, University of Ìbàdàn, Ìbàdàn.

Henderson, W.O. (1976). *The Life of Friedrich Engel*. London: Francais Company Ltd.

Ìṣọ̀lá, A. (2009). *Ayé Yẹ Wọ́n Tán*. Ìbàdàn: D.B Martoy Books.

Ogbeidi, M.O. (2012). "Political Leadership and Corruption in Nigeria Since 1960: A Socio-Economic Analysis". *Journal of Nigeria Studies*, 1(12).

Ògúndélé, B. (2001). "Social Inequality and Social Stratification". (Eds.) Olurode, L. and Soyombo, O. *Sociology for Beginners.* Lagos: John West Pub.

Ògúnṣínà, B. (2006). *Sociology of the Yorùbá Novel: An Introduction*. Ilorin: Integrity Publication.

Òkédìjí, O. (1973). *Rẹ́rẹ̀ Rún*. Ìbàdàn: Oníbọn-òjé Press and Book Industries.

Okùnadé, B. (2008). "The Big Challenge". *An Inaugural Lecture.* University of Ìbàdàn.

Ọnàbánjọ, O.D. (2011). "The Centrality of Women in Moral Tradings in Yorùbá Family System in Gender and Behaviour". Vol. 9 (1).

Ọnàbánjọ, O.D. (2013). "Social Stratification and Mobility". in *Essential of Sociology*. Abórìṣàdé, R.; Ọmọbọ̀wálé, A.O. and Ọláyínká, A. (Eds.). Ìbàdàn: University Press.

Onigu, O. and Ogionwo, W. (2006). *An Introduction to Sociological Studies*. Ìbàdàn: Heinemann Educational Books.

Ọ̀pẹ̀fèyítìmí, A. (1997). *Tíọ́rì àti Ìṣọwọ́lò-Èdè*. Òṣogbo: Tanímẹ̀hìnọ̀la Press.

Oyèbámijí, A. Kọ́lá (2015). "Leadership Oppression and Emancipation of the Masses as Reflected in *Ayé Yẹ Wọ́n Tán,* In *Àgọ́-Ìwòyè Journal of Languages and Literary Studies*, o.i. 128-159.

## End Note

[1] www.Meriam-Webster.com/dictionary accessed on January 4, 2017..